AKIYESI

Ẹ sare tete wa ra awọn ọja ti o ya nile wọny :-
Cash and Rent Receipt 6s dozen, £2 15s gross. Calendar 1958, 4s 6d dozen, £2 8s gross, Gbedegbeyo Hausa £1 4s dozen £12 8s gross, Goldsmith Receipt, complete set 17s 6d, ati orinirisi oja bẹ.
Ante Iwe fun Soṣi, Ile-Iwe, Egbe ati bebe, ao tẹ kiakia, yio si te yin lorun. E kowe si Manager:-

*Iyeru Press and Bookshop*
*68, Clifford Street,*
*Ebute-Metta.*

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE- IMARO
APA KẸTA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street.
Postage Extra

VOL. I No. 35. WEDNESDAY 26, FEBRUARY — MARCH 4, 1958 KỌBỌ KAN

# Awon "OLUKO" Tun Fe Da Ise Sile, Nibo Ni Ao Gba?

O fere maiti to iwon osu kan nisisiyi ti gbogbo awon oluko ti o nko awon omo wa ni iwe ninu ilewe won ti gbogbo won binu fi ise oluko sile, nitoripe owo osu won kere.

Ọgbẹni E. E. Esua, ti o nṣe akọwe awọn ẹgbẹ olukọ tun da ọrọ na ro, o ni ki awọn olukọ pada si ẹnu iṣẹ wọn, ki nwọn fi ẹr yanju ọrọ na. Sibẹsibe ohun ti awọn ẹgbe olukọ nlẹ, kosi eyiti Ijọba ṣe fun wọn nibẹ.

Awọn ẹgbẹ olukọ tun ṣe ipinnu titun miran nisisiy wipe, bi o ba di ọjọ kẹta oṣu March ti Ijọba ko fun wọn ni esi pataki kan awọn yio tun binu da iṣẹ silẹ.

O yẹ ki a ran ara wa leti wipe dida ti awọn oluko ilewe daṣẹ silẹ nijọsi jo fa sababi ti awọn ọmọ ilewe fi nlọ rin irinkurin kiri de ipo ti awọn fi bẹrẹ si mu wọn, nigbati nwọn kori ilewe lọ. A fi eyi bẹ Ijọba ki nwọn wa wọrọkọ fi ṣe ada, ki ọrọ ilewe ba le di ẹrọ.

## OLE KO ILE ADAJO KAN

Ni owurọ ana (Friday 22) ni awọn ole ko ile adajọ F. A. S. Ogunmuyiwa ti o adajọ ni Ebute Metta ni ogba ododo ( Botanical Garden Court ). Wọn ko ile rẹ ti o wa ni Ọlọnade, ibiti atẹgun ngba wọle ni wọn gba ko ile rẹ.

Adajọ na ri wipe ekini, gbogbo aṣọ yoruba ohun ti o ju igba lọ ti oun ko sinu kọbọdu ni wọn ti ko lọ, ekeji aimoye awọn ṣẹti olowo ribiribi ti salọ, ẹkẹta gbogbo awọn aṣọ oyinbo rẹ wa ni alafia, ẹkẹrin aṣọ fẹlẹfẹle meji (Nylon Shirts ) eyi wọ ọkankan jẹ pọun manit sile mrun ti oun ra ni ọsẹ ti o koja, wọn ko fi ọwọ kan awọn eleyi.

## AWON IWE KOSEMANI

Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Esin Ojisẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan a ti Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbeyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Iwe Itumọ Ala ati Ami Ara 3/6d
Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 2/6d

Akiyesi:- Ọpọlọpọ onibara wa ni ko mọ ile-iṣẹ wa ni Mushin, a fi eyi si eti igbọ wọn pe ki wọn ma lọ ra POSTAL ORDER ni POST OFFICE pẹlu Stamp 1/- ki wọn fi ranṣẹ si wa, nwọn yio si ri ọja wọn gba kiakia.

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada

J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin.




## ONISOWO KAN DI ISOWO GBOMO-GBOMO

Okunrin kan ti o nṣe owo Rọba, ni a gbọ wipe o lọ ra Roba ni agbegbe ilẹ Warri. Bi o ti npada bọ wa lo ri ọmọdebinrin kan loju ọna, lo ba gbe sori kẹkẹ Basikulu, lo ba ngbe ọmọ na lọ tayọ ibiti ọmọdebinrin na fe sọkalẹ.

A gbọ wipe nṣe ni ọmọ na bẹrẹsi sọkun ki awọn ọlọpa to wa fura si. A ṣe nigbati ọmọ nsọkun, o gbe epinni le ọmọ lọwọ ki o maṣe sọkun mọ, ibẹ ni awọn ọlọpa ti rin ọkunrin na mọlẹ, ki adajọ to wa ṣa si ẹwọn ọdun mẹrin.

Elubọ lo wa ra lọja, ọmọ ẹran ṣẹ'de inu igba? Onisọ-Rọba di onisowo eru.

## WON JU TEGBON TABURO S'EWON LEHIN NA NWON TUN FAINI WON FUN OLONTIRIN

A ju awọn meji kan tẹgbọntaburo sẹwọn oṣu kankan ni ana lati ẹnu adajọ kan ni Ebute-Metta fun ọlọntinrin ni dede agogo mejila oru, ṣugbọn adajọ na yi tun ro wo, o si ni ki wọn san pọun marun ikankan wọn.

Tẹgbọntaburo na, Funmilayọ Ejirẹ ọmọ ọdun marun dinlogoji ati Titilọla Aduni ọmọ ọdun kankan -dinlọgbọn sọ wipe awọn jẹbi fun ẹṣẹ wọn. Ko si ẹniti o gbeja wọn.

Adajọ na ri wọn ti wọn nrin kakiri ni ore King George Avenue Yaba ni ọjọ ogun oṣu yi.

Adajọ na bere lọwọ wọn bi wọn ti gbeyawo ṣugbọn ko si eyi ti o dahun ninu wọn. Alatako na si wipe irinsi wọn jẹ ki a ro wipe irinkiri wọn ni di

Lẹhin igbati adajọ ti dafọ ẹwọn oṣu kọkan fun ikankan wọn, awọn agbẹjọro meji dide gẹge bi ọrẹ ile ẹjọ wọn si bẹbẹ fun anu.

Adajọ gba ẹbẹ wọn o si ge ẹwọn wọn si pọun-marun enia kankan wọn.

Ẹ MA KA IROHIN IMOLẸ KI Ẹ SI MA POLOWO ỌJA YIN SINU RẸ.

